# Bibeli fun awon omode

## Ajinde akoko



Ikosile gba owo: Edward Hughes

Ayaworan: Janie Forest

Olu'lo: Lyn Doerksen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2013 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Arabinrin na duro
si eti apata na,
oju ekun re nwo
iran buburu na.
omo re nku lo.
Iya na ni Maria,
osi duro leti ibiti
akan Jesu mo
agbelebu.





Bawo li gbogbo eyi
se bere? Bawo li Jesu
se maa pari aye didara
si aye itiju ni? Bawo li
Olorun se maa
fi omo re sile
lati ku sori
igi agbelebu?
Se Jesu o mo
eniti ohun je ni?
Tabi Olorun
kose dada ni?



Rara o! Olorun
se dada. Jesu ko se
asise. Jesu mo wipe
a o pa ohun gba owo
awon eni ibi. Nigbati
Jesu wa ni omode,
Simeoni arugbo ti
so fun Maria ohun
ibi to nbo wa sele.



Ojo die ki ato pa Jesu, arabinrin kan wa lati wa da ororo iyebiye si ese Jesu. “O n da owo nu” awon omo ehin re wi. “Oti se ise rere” Jesu wi bayi. “O se eyi fun isinku mi”. Iru oro kayefi wo re!

Lehin eyi, Judasi, okan ninu omo ehin mejila, gba lati fi Jesu han fun awon alufa agba pelu ogbon wura.





Li ajo irekoja awon Ju, Jesu je ounje igbehin pelu awon omo ehin re. o so ohun iyanu fun won nipa Olorun ati awon ileri re si awon to feran re. Jesu si fi akara ati omi fun won lati pin. Eyi ni lati ran won leti wipe Jesu fi ara ati eje re fun wa fun idariji ese.

Jesu si so fun awon omo ehin re wipe a o fi ohun han awon omo ehin re yio si fonka. "Emi ko ni salo", Peteru wi bayi. "Ki akuko to ke, iwo yio komi sile leemeta," Jesu wi.





Li oru ojo na, Jesu lo lati gbadura ninu ogba Getsimani. Awon omo ehin re ti owa lodo re sun lo fonfon. “Baba a mi”, Jesu gbadura, “… Jeki ago yi re koja lori mi, sugbon kiise bi mo tife, Ife re ni ko se.”

Lojiji, opo ero wonu ogba, Judasi lo siwaju won. Jesu ko ja, sugbon Peteru ge eti okunrin kan sile. Lai pariwo, Jesu fi owo kan eti arakunrin na osi wo san. Jesu mo wipe ki amu ohun pelu ife olorun fun ohun.



Awon eyi mu Jesu
lo si ile Alufa agba.
Nibe, awon agba Ju
so wipe ki Jesu ku.
Nitosi, Peteru duro
leba ina awon eru
osi nworan.



Leemeta li awon
eniyan wo Peteru
won si wipe “Iwo wa
pelu Jesu!” Leemeta
Peteru ko eyi, gegbi
Jesu se wi. Peteru
gegun o si bura.



KUKURUKUUUU!



Gele, akuko ke. O dabi
ohun Olorun si Peteru.
O ranti oro Jesu,
Peteru sonkun kikoro.



Judasi pelu bara je. O mo wipe Jesu ko jebi ese Kankan. Judasi gbe ogbon wura pada sugbon awon alufa ki yio gba.



Judasi so
owo na sile, o
jade lo – o si
pokun so.



Awon alufa mu Jesu to Pilatu wa, Gomina Romu. Pilatu so wipe, “Emi ko ri ese kan pelu okunrin yi.” Sugbon awon eniyan gbogbo wipe, “Kan mo agbelebu! Kan mo agbelebu!”

Nigbeyin, Pilatu gbo, osi pase ki akan Jesu mo igi agbelebu. Awon Omo-ogun gba Jesu lese, tu ito si loju, won si naa legba.  Won de ade egun lee lori.  Won si kan mo igi agbelebu lati ku.



Jesu mo wipe ohun yio ku iku oro yi. O si mo wipe iku re yio mu idariji ese wa fun awon to gbekele ohun. Ole meji li akan pelu Jesu. Okan gbagbo – o losi paradise. Ekeji ko gbagbo.



Lehin ijiya pipe, Jesu wipe "o ti pari," o si ku. Ise re ti pari. Awon ore re sin sinu isa oku titun.




Awon omo-ogun
Romu so ibi iboji.
Kosi eniti o le
wole - tabi jade.

Bi eyi ba je opin itan yi, iba mu are wa. Sugbon Olorun se ohun ara kan. Jesu ko ku!



Li kutukutu owuro ojo akoko
ninu ose, awon omolehin
Jesu kan ri iboji wipe
osi sile.  Nigbati won
wo inu re, Jesu
kosi nibe.



Arabinrin kan lo duro, o sonkun li iboji. Jesu farahan! O sare loso fun awon omo ehin toku. “JESU WA LAAYE! JESU TI PADA WA LATI ISA OKU!”





Laipe, Jesu pada waba awon omo ehin re, o si fi owo re han won. Otito ni. JESU WA LAAYE SI! O DARIJI Peteru ti o ko sile, o si wi fun awon omo ehin re ki won so fun gbogbo eniyan nipa ohun. O si pada losi orun ti oti wa nigba keresimesi akoko.

Ajinde akoko

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Iwe Matthew 26-28, Luku 22-24, Johannu 13-21

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi 119:130

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.